Awọn adari kan maa jẹ, ẹ maa mọ ẹ si maa ṣe atako, ẹni ti o ba mọ, o ti bọ, ẹni ti o ba ṣe atako, o ti la, sugbọn ẹni ti o ba yọnu ti o si tẹle

Lati ọdọ Umu salamah iya awọn olugbagbọ- ki Ọlọhun yọnu si i-: Dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe: "Awọn adari kan maa jẹ, ẹ maa mọ ẹ si maa ṣe atako, ẹni ti o ba mọ, o ti bọ, ẹni ti o ba ṣe atako, o ti la, sugbọn ẹni ti o ba yọnu ti o si tẹle" wọn sọ pe: Njẹ a ko nii ba wọn ja? O sọ pe: "Rara, lópin ìgbà tí wọ́n ba ṣi n kirun".
[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe awọn olori kan maa jẹ lé wa lori, a maa mọ awọn kan ninu awọn iṣẹ wọn; nitori pe wọn ba nnkan ti wọn mọ ninu Sharia mu, a si maa tako awọn kan ninu wọn; nitori wọn yapa ìyẹn, Ẹni ti o ba korira ibajẹ pẹlu ọkan rẹ, ti ko kapa lori atako; o ti bọ kuro ninu ẹṣẹ ati ṣọbẹ-selu, Ẹni ti o ba kapa lori atako pẹlu ọwọ tabi ahọn, ti o wa tako ìyẹn fun wọn o ti la kuro nibi ẹṣẹ ati kikopa nibẹ, Ṣugbọn ẹni ti o ba yọnu si iṣe wọn ti o si tẹle wọn lori rẹ, o maa parun gẹgẹ bi wọn ṣe parun. Lẹyin naa wọn bi Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- leere pe: Njẹ a ko nii ba awọn adari ti wọn ṣe pe eyi ni iroyin wọn ja? O wa kọ fun wọn kuro nibẹ, o wa sọ pe: Rara, lópin ìgbà tí wọ́n ba ṣi n gbé ìrun duro láàárín yin.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3481